# ỌDỌ-AGUTAN ỌLỌRUN

## Ifihan 5:1-14

## ẸKỌ 461 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Yiyẹ, li Ọdọ-Agutan na ti a ti pa, lati gbà agbara, ati ọrọ̀, ati ọgbọ́n, ati ipá, ati ọlá, ati ogo, ati ibukún" (Ifihan 5:12).**

**I Iwe Ti O Ni Edidi Meje**

1 Ọlọrun mu Iwe ti o ni edidi naa lọwọ, Ifihan 5:1;Daniẹli 12:4, 9
2 Ibeere yii ni a beere pé: "Tali o yẹ lati ṣí iwe na?" Ifihan 5:2-4
3 Kiniun Ẹya Juda bori lati ṣi Iwe naa ati lati tú edidi rẹ̀, Ifihan 5:5;Heberu 7:14

**II Ọdọ-Agutan Alaaye**

1 Ọdọ-Agutan kan duro laaarin Itẹ naa, Ifihan 5:6; 13:8;Isaiah 53:7; Johannu 1:29, 36
2 Ọdọ-Agutan naa gba Iwe naa ni ọwọ́ Ọlọrun, Ifihan 5:7
3 A fi ẹ̀yẹ ati ọlá fun Ọdọ-Agutan naa, Ifihan 5:8;7:9, 10

**III Orin Titun**

1 "Iwọ li o yẹ," ni ọ̀rọ̀ orin titun naa, Ifihan 5:9, 10
2 Awọn angẹli Ọrun fi iyin fun Ọdọ-Agutan naa, Ifihan 5:11, 12
3 Gbogbo ẹda wolẹ fun Ọlọrun ati Ọdọ-Agutan naa, Ifihan 5:13, 14

## ALAYE

**Ifihan**

Ọkàn Johannu ti ni lati kún fun ayọ̀ lati igba de igba bi a ti n ṣi Ifihan Jesu Kristi paya ni ṣisẹ-n-tẹle. Johannu ti ri Kristi ninu ogo Rẹ̀ o si ti gbọ́ ọrọ Rẹ̀. O ti gbọ́ o si ti kọ iṣẹ́ ti a rán si awọn ijọ meje silẹ, lẹyin naa ni o tun ri anfaani ti o yanilẹnu pupọ, lati ri Itẹ Ọrun ati Ọlọrun bi o ti joko lori Itẹ naa. "Yi itẹ́ na ká si ni itẹ́ mẹrinlelogun: ati lori awọn itẹ́ na mo ri awọn àgba mẹrinlelogun joko, ti a wọ̀ li aṣọ àlà; ade wura si wà li ori wọn" (Ifihan 4:4). Pẹlu awọn àgbà ti o wà yi Itẹ naa ká ni awọn ẹda alaaye mẹrin, awọn ti kò dẹkun ati maa fi ogo ati ọlá ati ọpẹ́ fun Ẹni ti o joko lori Itẹ́.

Johannu ri gbogbo eyi, ṣugbọn ọrọ ti o jade si i ni, "Goke wa ihin, emi o si fi ohun ti yio hù lẹhin-ọla hàn ọ" (Ifihan 4:1). Bibeli sọ fun ni pe Ọlọrun ti pese nnkan wọnyii fun awọn ti wọn gba Ọmọ Rẹ̀ ti wọn si gba A gbọ́, fun awọn ti wọn fẹ Ẹ ti wọn si n sìn In. "Ẹniti o ba ṣẹgun ni yio jogún nkan wọnyi; emi o si mã jẹ Ọlọrun rẹ̀, on o si mã jẹ ọmọ mi" (Ifihan 21:7). "Nwọn o si mã ri oju rẹ̀; orukọ rẹ̀ yio si mã wà ni iwaju wọn … nwọn o si mã jọba lai ati lailai" (Ifihan 22:4, 5).

Gbogbo awọn ti o kọ ipe Kristi, awọn ti wọn kọ̀ lati sin In, awọn ti wọn ṣaigbọran si ofin Rẹ̀, wọn ko ni padanu Ọrun nikan, ṣugbọn ohun kan ni o ṣi silẹ fun wọn: lati ṣegbe titi ayeraye, ni idalẹbi sinu adagun iná. Pẹlu idalẹbi buburu yi, ati idalẹbi fun ẹṣẹ ati imọ̀ ti o daju nipa egbe ayeraye, ki ni ṣe ti ẹnikẹni yoo tun fẹ lati wà ninu igbesi-ayé aiwa-bi-Ọlọrun. Ni idakeji ẹ̀wẹ̀, o yẹ ki ayọ ti a n ri gbà nipa gbigbe igbesi-ayé Onigbagbọ́, pẹlu ẹ̀bun Ọlọrun ti a fi kun un, iye ainipẹkun, tó fun ẹnikẹni lati sin Kristi ati Ọlọrun.

**Iran Johannu**

Ninu Ifihan naa, Johannu ri i ni ọwọ ọtun Ẹni ti o joko lori Itẹ́ naa, Iwe kan ti a kọ ninu ati lẹyin, ti a fi edidi meje di. Ọlọrun fi Iran naa hàn lati le fi han awọn iranṣẹ Rẹ̀ ohun ti yoo ṣẹ ni lọọlọọ, ṣugbọn Iwe ti o ni edidi yii fa idaduro diẹ ninu eto ifihan naa. Angẹli alagbara kan kede ọ̀rọ yii, "Tali o yẹ lati ṣi iwe na, ati lati tú èdidi rẹ̀?" Ki iṣe agbára eniyan ni a n wá lati fi ṣi èdidi naa, bi o ba ṣe bẹẹ ni angẹli alagbara naa i ba ti le ṣi Iwe naa.

Johannu sọkun gidigidi nitori a kò ri ẹnikan, ani lara awọn angẹli Ọlọrun paapaa, ti o le tú awọn edidi, ki o si ṣi Iwe naa. Bi Iwe yii ba wa ni titi, a o du ijọ, ayé ati Ọrun ni imoye ọrọ ti o wà ninu rẹ̀. Ọpọ eniyan ni wọn ro pe Iwe yii ni i ṣe pẹlu iye-owo irapada. A ni lati kọ́ mú eto Ọlọrun fun igbala araye ṣẹ ki a to le tú èdidi naa.

Bi Johannu ti n sọkun, ọ̀kan ninu awọn agba naa mu ọrọ itunu yii wa: "Máṣe sọkun: kiyesi i, Kiniun ẹ̀ya Juda, Gbòngbo Dafidi, ti bori lati ṣi iwe na, ati lati tú edidi rẹ̀ mejeje." Ọrọ Bibeli ni o le ṣapejuwe iran iyanu naa ti Johannu ri: "Li arin itẹ́ na, ati awọn ẹda alãye mẹrin na, ati li arin awọn àgba na, Ọdọ-Agutan kan duro bi

eyiti a ti pa, o ni iwo meje ati oju meje, ti iṣe Ẹmi meje ti Ọlọrun, ti a rán jade lọ si ori ilẹ aiye gbogbo." Ẹni yii jade wá O si gba Iwe naa ni ọwọ́ Ẹni ti o joko lori Itẹ́ naa.

**Yiyẹ**

Ki ni ohun ti o mú Ọdọ-Agutan naa yẹ lati gba Iwe naa ati lati tú edidi rẹ̀? Iwo Rẹ̀ meje ha mu Un yẹ bi? Ni tootọ iwo meje Ọdọ-Agutan naa n tọka si Alagbara ju lọ nitori ti iwo duro fun agbara, meje si jẹ iye nnkan ti o kún tabi ti o pé ninu gbogbo Iwe Mimọ́. Tabi oju meje, Ẹmi meje ti Ọlọrun: wọnyii ha ni awọn ohun amuyẹ? Lẹẹkan si i eyi jẹ iye nnkan ti o pé ti o si n sọ nipa ọgbọ́n, oye ati imọ. Awọn amuyẹ wọnyii ṣọwọn, wọn si yanilẹnu, wọn si ni àye ati iṣẹ ti wọn; ṣugbọn ki i ṣe nnkan wọnyii ni o mú Ọdọ-Agutan naa yẹ lati tú èdidi naa. "Tali o yẹ lati ṣi iwe na?" Jesu Kristi, Kiniun, Ọdọ-Agutan, jade wá! Ni igba akọwa Rẹ̀ O jẹ́ Ọdọ-Agutan lati fi ara Rẹ̀ rubọ fun ẹ̀ṣẹ wa (Johannu 1:29). Ni igba wiwá Rẹ̀ lẹẹkeji Oun yoo jẹ́ Kiniun, ti O tobi ti O si ni agbara lati ṣakoso ati lati jọba.

Ipo Kristi bi Ọdọ-Agutan Kalfari fun etutu ni o mu Un yẹ lati gba Iwe naa ati lati tú edidi rẹ̀. Awọn ẹda alaaye mẹrin naa, ati awọn agba mẹrinlelogun naa wolẹ niwaju Ọdọ-Agutan naa ni ẹ̀yẹ ati ijọsin. Orin titun dún jake-jado gbogbo ilẹ Ogo. A tun fẹ ṣi omiran paya ninu awọn ohun ijinlẹ nla Ọlọrun. "Iwọ li o yẹ lati gbà iwe na, ati lati ṣi èdidi rẹ̀: nitoriti a ti pa ọ, iwọ si ti fi ẹ̀jẹ rẹ ṣe irapada enia si Ọlọrun lati inu ẹyà gbogbo, ati ède gbogbo, ati inu enia gbogbo, ati orilẹ-ède gbogbo wá; iwọ si ti ṣe wọn li ọba ati alufa si Ọlọrun wa: nwọn si njọba lori ilẹ aiye." Ọrọ orin yii wú angẹli lori, nitori kò pé lẹyin naa ni ẹgbẹẹgbẹrun ọ̀na ẹgbẹẹgbẹrun awọn angẹli busayọ pé, "Yiyẹ li Ọdọ-Agutan na ti a ti pa, lati gbà agbara, ati ọrọ̀, ati ọgbọ́n, ati ipá, ati ọlá, ati ogo, ati ibukún."

**Awọn Ẹni-Irapada**

A ṣe ifihan nihin yii nipa ẹni ti awọn ẹda alaaye mẹrin ati agba mẹrinlelogun ni i ṣe: wọn jẹ́ aṣoju awọn ẹni-irapada ayé. Wo o bi ipo wọn ti ga to ni Ọrun: wọn wà yi Itẹ́ Ọlọrun ká, wọn n fi iyin ati ijuba sin In. Ọlá Jesu ni o mú wọn dé àye ati ipò wọn, nitori Oun ni O fẹ fi ẹmi Rẹ̀ lelẹ lati rà wọn pada.

Gbogbo eniyan ni anfaani ṣi silẹ fun lati ṣe alabapin ninu eto ati ipe irapada, ṣugbọn kiki iye awọn ẹni ti o ba jẹ́ ipe naa, ti wọn si ṣe oloootọ de opin ni a o gbala. Iṣubu sinu ẹ̀ṣẹ ti run araye, ko si si ireti ati pada sọdọ Ọlọrun, bikoṣe nipasẹ eto Ọlọrun. Awọn eniyan ti wá orișirișì ọna lati ṣiṣẹ igbala ti wọn, ṣugbọn ko si ireti rara fun wọn ayafi bi Jesu ba ṣe Alagbawi fun wọn. Oun nikan ni Alarina kan ṣoṣo laaarin Ọlọrun ati eniyan.

Eyi ni ọna Ọlọrun, iṣẹ alarina Kristi si ti fi itoye rẹ̀ hàn ninu ogunlọgọ iye awọn ti o gba A, sibẹ ogunlọgọ si i ni o ṣi le wá bi wọn ba fẹ́. Nigba ti a ba n ronu nnkan wọnyii, ko ha yẹ ki ọkàn wa kún fún ọpẹ? "Ẹnyin mọ̀ ore-ọfẹ Oluwa wa Jesu Kristi, pe bi on ti jẹ ọlọrọ̀ ri, ṣugbọn nitori nyin o di talaka, ki a le sọ nyin di ọlọrọ̀ nipa aini rẹ̀" (2 Kọrinti 8:9). "Emi nlọ ipèse àye silẹ fun nyin. Bi mo ba si lọ ipèse àye silẹ fun nyin, emi o tún pada wá, emi o si mu nyin lọ sọdọ emi tikarami; pe nibiti emi gbé wà, ki ẹnyin le wà nibẹ pẹlu" (Johannu 14:2, 3). Ẹkọ wa ti fun wa ni firífirí àyè ologo ti a pese silẹ nì. Ọlá Jesu ni gbogbo rẹ̀.

Ni ọjọ nla nì ti Jesu jade wá lati gba Iwe naa, awọn ẹda alaye fi iyin fun Un, awọn alagba dohùn pọ̀ kọ orin titun naa, awọn angẹli Ọrun fi ohun rara gbé ẹ̀yẹ Rẹ̀ ga, gbogbo ẹda si dapọ lati juba Rẹ̀. Ẹ jẹ ki awa naa yin In pẹlu! "Jẹ ki ohun gbogbo ti o li ẹmi ki o yin OLUWA. Ẹ fi iyin fun OLUWA" (Orin Dafidi 150:6).

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni o jẹ́ abami nipa Iwe ti Ọlọrun mú ni ọwọ ọtun Rẹ̀?
2 Ta ni o yẹ lati ṣi Iwe naa?
3 Orukọ meji wo ni a fún Kristi nihin yii?
4 Ṣapejuwe bi awọn ẹda alaaye mẹrin nì ati awọn agba mẹrinlelogun ni ti n ṣe?
5 Ki ni orin titun wọn?
6 Angẹli meloo ni o dapọ lati bá wọn yin Ọdọ-Agutan?
7 Ẹgbẹ́ miiran wo ni a kà mọ́ ijọsin gbogbo gboò yii?